*Ireti Eda…!*

**EPISODE 22**

**<u>Characters</u>**

*Lukman*
*Iyabo*
*Mr Animashaun*
*Mrs Animashaun*
*Babalawo*
*Baba Wasiu*

---

**Scene 1**
**Ibadan. Lukman's residence!**

1. **LUKMAN**: **<u>(SINGING AN ISLAMIC SONG. OBVIOUSLY HAPPY)</u>**
2. **IYABO**: (**SURPRISED**) Ah Baba Abokede. Ibi yi lewa
3. **LUKMAN**: Iyabo, kaabo. Aya mi atata. Bawo ni party ti o lo fun?
4. **IYABO**: (**SKEPTICALLY**) Party ti se ara e o jare. Kilode ti e nrerin bayi, afi bii eni to je 'baba ijebu'?
5. **LUKMAN**: Inumi kan ndun ni. Mo gba call kan to dunmininu
6. **IYABO**: (**CURIOUS**) Call? Lati odo tani?
7. **LUKMAN**: Lati Ilorin. (**HAPPILY**) Abokede fe se igbeyawo
8. **IYABO**: (**SHOCKED, PAUSE**) Abokede wo?
9. **LUKMAN**: Ah ah? Se Abokede pe meji ninu ebi yi ni?
10. **IYABO**: (**DISBELIEVINGLY**) Abokede fe se'gbeyawo? Bawo?
11. **LUKMAN**: Bawo ni eeyan tun se nse igbeyawo? Oko e ma mu awon ebi e wa, won ma wa se 'momi n mo o', won a de se igbeyawo.
12. **IYABO**: (**DEFENSIVELY**) Ema da mi lebi wipe mo nbere o, nitori iru igbeyawo gbajawiri yii o ye emi o. igba wo lo sese lo si Ilorin ti o tin soro igbeyawo pelu omo okunrin ti eeyan o mo
13. **LUKMAN**: ko kin se pajawiri o. oun ati omo okunrin na ti ba ara won rin fun ojo melo bayi o
14. **IYABO**: (**INCREDULOUSLY**) E ti mo nipa won tele ni?
15. **LUKMAN**: Mo ti mo wipe o ni eni ti onfe ni Ilorin. Mi o kan ti mo omokunrin naa sha.
16. **IYABO**: (**WITH SUPPRESSED ANGER**) Oga o. so emo, e o ko so funmi ni?
17. **LUKMAN**: Sebi mo de tin so fun e bayi?
18. **IYABO**: (**SARCASTICALLY**) Enh enh? So kilode ti ewa se nso funmi nisinyi?

19. **LUKMAN**: Nitori a ni lati bere si ni se ipalemo igbeyawo naa ni

20. **IYABO**: (**CLAPS HER HANDS**) Eyin ati ta lo fe se ipalemo?

21. **LUKMAN**: Ah ah? Oro e o yemi o Iyabo. Omo wa ni Abokede. ta ni o tun ma se ipalemo ti o ban se awa?

22. **IYABO**: ko kin somo temi o. omo yin ni. Mo mo eye omo ti mo bi o.

23. **LUKMAN**: Iyabo, iru oro wo lo nso lenu yi? Omo e ni Abokede. abi iwo ko lo to dagba ni? Kilode ti o nso gbogbo oro to nso yi?

24. **IYABO**: (**POUNCING**) Oh, so, e mo wipe bi omo lo je simi, eede so funmi pe Abokede ti nfe eeyan kan ni Ilorin enh? Abi you know she is like a daughter to me and you kept the relationship a secret from me enh? Abi, won ti so fun yin pe teba so funmi maa pa ni?

25. **LUKMAN**: (**SHOCKED**) Iyabo, kini gbogbo jati jati yi? Ki lo de to nso gbogbo oro rirun yi?

26. **IYABO**: kilode ti mi o ni so? Abi kilode ti eyin na fi iru nkan beeyen bo funmi?

27. **LUKMAN**: Mi o fi nkankan bo fun e o Iyabo. (**CALMLY**) Oda, iyawo mi, maa binu. Eni yi ni won sese so funmi nipa iyawo ti won ma se. o mo wipe mi o le fi nkankan bo fun e.

28. **IYABO**: Eti fi bo already

29. **LUKMAN**: Oda. Maa binu. Gba owo yi

30. **IYABO**: Owo kini?

31. **LUKMAN**: Fi owo yen seto ounje ati nkan mimu fun igbeyawo. Gba owo yi naa….

32. **IYABO**: Fun kini?

33. **LUKMAN**: Iwo lo niyen. Mo mo pe waa fe ra aso ati bata tuntun fun igbeyawo yen. Omo wipe iwo ni iya iyawo lojo yen.

34. **IYABO**: (**RELUCTANTLY**) Hmm. Baba Abokede, ti o ba nse nkan ti awon eeyan ma so ni, mi o ni ba yin lowo si rara o. nitori, ee ti e kamikun rara lori oro yi o.

35. **MUSIC**: **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 2**

**Ilorin! Animashaun's residence.**

36. **SFX**: <u>**DOOR OPENS AND CLOSES**</u>

37. **MRS ANIMASHAUN**: (**SIGHS TIREDLY**) Eku ile o

38. **MR ANIMASHAUN**: Bisi, ibo lo ti ri gbogbo bag to ko dani yi?

39. **MRS A**: Ah ah? She bi a n palemo igbeyawo Bello ni?

40. **MR A**: Mo mo.

41. **MRS A**: Awon nkan ti a ma nilo ni mo lora. Aso tuntun nnkankan. Odindin Ibadan la nlo, ao gbodo dabi eni ti iya nje.

42. **MR A**: (**CHUCKLES**) ko ya mi lenu jare. Iyawo mi to mo owo naa

43. **MRS A**: Ah well, nina lowo

44. **MR A**: Sugbon maa naa alai nidi o, iya Bello. Ko ti e nse nisiyin ti mo ti padanu owo pupo bayi.

45. **MRS A**: (**CONSOLING**) Maa worry. Olorun a daa gbogbo e pada.

46. **MR A**: Mo mo! Mi o tie complain nitori mo mo wipe ori igbeyawo Bello lo nna owo si. Inumidun pe omo mi naa ti di okunrin o.

47. **MRS A**: Beeni o. ojo melo seyin, ni mon baa sere pe o ma funmi ni awon omo'mo repete.

48. **MR A**: (**LAUGHS**) Really? Ki lo wa so?

49. **MRS A**: O ni, (**MIMICKING BELLO**) Ah mummy, mi o ni bi omo repete ju eyi ti mo le toju lo o. mo fe fun won ni iru itoju ati igbe aiye ti eyin ati daddy fun emi ati Shade

50. **MR A**: (**CHUCKLES**) Bello lo so gbogbo iyen? (**BOASTFULLY**) Se ori bayi, mo train omo yen daada.

51. **MRS A**: (**CLAPPING HER HANDS**) So, iwo nikan lo train e dada abi. Anyway, mo so funn pe oni atileyin awa mejeeji. Ti oba fe to ebi e bii ti oba se wun, then, a wa leyin o gidigba.

52. **MR A**: Yes, of course! Owo okin se iyonnu rara.

53. **MRS A**: Ifeto-somo-bibi gann o kin nse nkan to won lotiti naa. Infact, ni hospital ijoba gan, ofe ni. So awon ololufe mejeeji le gbe aiye won bi oba se wun won. Inu temi tie ndun gan. Omo Abokede yen, omo dada ni. Mo nife e gann.

54. **MR A**: Ati emi na. ebi to da naa de loti wa. Mo like won gann nigba ti mo pada aunty e Wosilat ati oko e, em,, Ajani

55. **MRS A**: Won o kan lowo ni

56. **MR A**: Mo ti pinu lati wa ise fun Ajani.

57. **MRS A**: (**HAPPILY**) Ah, iyen naa da. Inu mi dun pe o ti e nfi ara e si gbogbo oro won yi.

58. **MR A**: Bi nba fi ara si, tani o ma se? omo mi ni Bello.

59. **MRS A**: (**CAREFULLY**) Omo e naa ni Folashade

60. **MR A**: Mo mo

61. **MRS A**: O de wunmi ki o fun oun na ni atileyin ni ibasepo ti oun na

62. **MR A**: Ibasepo osi wo? Pelu omo Ojo? Ka ma ri. Lai ku mi? koi ti ri oko o, ko ya beere si nfi oju sita fun elomi.

63. **MRS A**: (**SCARED**) Baba Bello, oro yi ose duro wo bayi o. omo yi o jeun. Oti n ru

64. **MR A**: Wobi Bisi, eri okan Sade ni ko je ko jeun. Ti oba ti su lati ma fi ebi pa'nu, aa jeun.

65. **MRS A**: Baba Bello, mi o le gbagbo pe oun so iru nkan ti o nso yi. Folasade ti leri pe oun ma para oun o. mi o de joko sibi kin ma duro ko para e

66. **MR A**: Bisi, omo mi ni Folashade. Mo de mo wipe gbogbo eyi ti o nse yen, ere lo nse.

67. **MRS A**: Omo mi nru lo, o de ni ere lo nse? Wo baba Bello, ooya lo pari nkan to wa laarin iwo ati awon Ojo o. emi oni je ko baye omo mi je nitori oro kan ti o nidi.

68. **MR A**: Omo mi ole fe omo Ojo se!

69. **MRS A**: (**PETULANTLY**) Hmmmm, nnkan ti oyi nso niyen abi? Emi naa a de mu ile aiye suu e. maa mu ile yi gbona fun e, waa ri!

70. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 3**

**Ibadan! Babalawo Ajani's shrine. Evening!**

71. **BABALAWO**: (**SINGING AND MAKING INCANTATIONS TO HIS GODS**)

72. **IYABO**: (**CLAPS HER HANDS**) Baaba o

73. **BABALAWO**: Tani yen o?

74. **IYABO**: Iyabo ni o.

75. **BABALAWO**: Wole!

76. **IYABO**: Ese o baaba.

77. **BABALAWO**: (**MAKES SOME MORE INCANTATIONS**) Iyabo. Kaabo.

78. **IYABO**: (**HURRIEDLY**) Baba, egba mi o. mo nilo iranlowo yin o

79. **BABALAWO**: (**LAUGHS EVILL**Y) Iyabo, ko le yami lenu. Igba ti o ba fe iranlowo nikan lo ma nde ibi. Inu orunmila o dun sii e

80. **IYABO**: Ah baba, ko ri bee. Ise ni. E mo wipe lati igba ti Abokede ti lo si Ilorin, emi nikan ni mo nda gbe, ni mo nda faa

81. **BABALAWO**: Iyen o ni ko ma ma wa leekankan lati wa dupe ore lowo Orunmila

82. **IYABO**: Ema binu simi baba. E bami be awon Orunmila.

83. **BABALAWO**: (**MAKES INCANTATIONS**) Won ti gbo e. kini o fe?

84. **IYABO**: Baba, Abokede tun ni o

85. **BABALAWO**: Ki lo tun se abokede? mo ro wipe Ilorin lo wa ni

86. **IYABO**: Beeni baba. Ilorin lo wa. Sugbon mo gbo wipe o ti se oriire nibe. O ti tun ti fe wo ile-iwe giga

87. **BABALAWO**: Enh enh?

88. **IYABO**: Baba, se nkan ti efe so niyen?

89. **BABALAWO**: Kini ese e lote yi?

90. **IYABO**: Baba, oriire yen gan, egbin lo je fun mi. Bawo lo se ma se oriire? Leyin gbogbo bi ti mo se lepa iku e to? won tun wa wipe o fe se iyawo. Pelu omo olowo.

91. **BABALAWO**: Ki lo wa fe bayi o Iyabo?

92. **IYABO**: Eje ka ya paa tutu bayi o. igbeyawo yen o gbodo seese.

93. **BABALAWO**: Iyabo, mo ti so fun e pe omo yen ti di koseemu. Ori e ti le ju. Oku iya ko figba kan fissile o

94. **IYABO**: Baba, ko si nkan to kan mi pelu iyen o. eyin ni babalawo to gbona ju ni gbogbo ilu wa yi, e o de seun ti ri. Egbodo ri nkan se soro mi yi o

95. **BABALAWO**: Hmm (**MAKES INCANTATIONS**) Nnkan ti ale se wa. Sugbon oni ewu gann o.

96. **IYABO**: Baba, maa se. olewu, kolewu. Igbeyawo yen o gbodo seese rara.

97. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 4**

**Ibadan! Lukman's house.**

98. **BABA WASIU**: (**SINGING LUKMAN'S PRAISE SONG**)

99. **LUKMAN**: (**EXCITEDLY**) Ah, Baba Wasiu, ore mi. maa wole bo. Mo ni iroyin ayo fun e

100. **B. WASIU**: Enh enh, Lukman. Kini yen?

101. **LUKMAN**: omo mi Abokede ni. O ti fe se igbeyawo

102. **B. WASIU**: (**EXCLAIMS HAPPILY**) Ah, iroyin ayo gba niyen o. nigbawo ni?

103. **LUKMAN**: Bi ose bi melo kan sii igba yi.

104. **B. WASIU**: (**BOASTFULLY**) Awa naa ni baba Iyawo.

105. **LUKMAN**: Beeni o. aa o ri emi she.

106. **BABA W**: (**CONCERNED**) Em… ore mi. ki lo ma wa sele si eko e o. Se igbeyawo yi, o ni dii lowo bayi? Abi, aa se fe loyun to be se iyawo tan

107. **LUKMAN**: (**CHUCKLES**) Ah, won ti mu Abokede ni ile-iwe giga. Ko ni pe lo si university ti Ilorin. O da npe Law ni won mu fun. Oun ati oko e de ti pinu lati dawo omobibi duro di igba ti oba ma pari eko e.

108. **BABA W**: (**HAPPILY**) Enh enh! Iyen lo da. Nkan to daa ju niyen. Mo ri wipe ara omo okunrin yen ti wa lona gan, oya tete mu Abokede sodo ki won to gbaa mo lowo.

109. **LUKMAN**: (**LAUGHS**) Oti setan igbeyawo ni. Mo gbo pe idile olowo loti jade

110. **BABA W**: Omo ire. Ta ti e lo ma ri iru omo Abokede yen, to ma le mu oju kuro? (**PRAYING**) Abokede! omo Shakirat. Abi okunrin abiro, obinrin abiye, ibeji, ibeta….

111. **LUKMAN**: (**INTERRUPTS, LAUGHING**) Ah! Baba Wasiu. Ma je ki Abokede gbo yen o. oun ati oko ti so pe awon ofe omo repete o

112. **BABA W**: Oh! Won fe se ifeto-somo-bibi niyen. Iyen daa o. owo o de kin se iyonnu fun won, sebi o ni olowo ni oko e

113. **LUKMAN**: Nnkan ti mo so fun niyen sugbon o ni ifeto-somo-bibi kin se nkan to won rara. Oni ofe gan ni ni ile-iwosan ijoba.

114. **BABA W**: Lukman, omo e ti lo Ilorin lo gbon wa ni o. a gbodo wee o. oya ni ki won ra pepper soup ati igo beer kan to tutu to woyin wa funmi.

115. **LUKMAN**: (**LAUGHS**) Baba Wasiu, ko si beer fun e loni. Ounje o nipe jina.

116. **BABA W**: Enh enh? Oda nigbayen o. (**STARTS SINGING AGAIN**)

117. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**